# IFARAHÀN ỌLỌRUN LORI OKE SINAI

**Ẹksodu 19:1-25; Heberu 12:18-25**

**ẸKỌ 60 – FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Kiyesi i, ki ẹ máṣe kọ̀ ẹniti nkilọ" (Heberu 12:25).**

## Sinai

Awọn Ọmọ Israẹli ti de aginju Sinai. Eyi ki i ṣe ilẹ ajeji fun Mose nitori nihin ni o ti n ṣọ́ agbo-ẹran baba iyawo rẹ̀ nigba ti o sá kuro ni ilẹ Egipti. Ni ibi Oke Horebu ni Ọlọrun ti ba Mose sọrọ lati inu igbẹ ti n jó, O si ran an pada si Egipti lati mu awọn eniyan Rẹ̀ ti o ti yàn jade. Sinai jẹ ibi giga kan laaarin awọn Oke Horebu, a si maa n lo awọn orukọ wọnyii, ọ̀kan fun ekeji. Awọn Ọmọ Israẹli yoo wà nihin fun bi ọdun kan, nihin ni a si ri awọn ohun ti o lọ́wọ̀ ju lọ ti o si dun mọ ni ninu iwe akọsilẹ Bibeli. Nihin ni Ọlọrun fi Ofin Mẹwaa fun ni.

Ọlọrun ba Mose sọrọ lati igba-de-igba ninu ọwọ̀n awọsanma ti o n ṣaaju wọn ninu irin-ajo wọn, nisisiyii awọsanma naa sọkalẹ gan an sori oke naa, Mose si goke lọ ba Ọlọrun sọrọ. Lẹyin ikú Mose a ka nipa rẹ pe, "Wolĩ kan kò si hù mọ́ ni Israẹli bi Mose, ẹniti OLUWA mọ̀ li ojukoju" (Deuteronomi 34:10). Wo iru ọpọ ibukun iyebiye ti Mose ti gba nitori o gbe igbesi-aye rẹ̀ patapata lati wu Ọlọrun!

## Ni Apa Iyẹ Idì

Oluwa sọ fun Mose pe ki o rán awọn Ọmọ Israẹli leti ni ti awọn iṣẹ-iyanu ti Oun ti ṣe loju wọn ni Egipti, ki o si tun rán wọn leti ọna ti Oun gba gbe wọn soke bi i lori iyẹ idì. Nigba ti idì kan ba fẹ kọ́ ọmọ rẹ bi ẹyẹ ti i fò, oun a ti wọn jade kuro ninu itẹ lati jẹ ki wọn fi iyẹ́ wọn fò. Ṣugbọn bi ọmọ idì naa kò ba le fo soke, tabi ti o ba fẹ̀ fi ori gba okuta, iya idì naa yoo fo sabẹ rẹ yoo si tun gbe e soke lori iyẹ apa rẹ̀, ki o ba le tun gbiyanju lati fò. Bakan naa ni Ọlọrun ti gbe awọn eniyan Rẹ̀ soke ti O si pa wọn mọ ki wọn má ba pa ara wọn lara. O ti fa wọn mọra gẹgẹ bi eniyan ọtọ̀. Eyi fi hàn bi O ti fẹran wọn to lai ka kikùn wọn si. Oun si n fẹ ki wọn fẹran Oun bẹẹ!

Ọlọrun sọ fun Mose pe bi awọn Ọmọ Israẹli yoo ba gbọran si Oun lẹnu, wọn yoo jẹ iṣura pataki fun Oun. A mọ̀ ohun ti iṣura jẹ: ohun ti o ṣe iyebiye fun ni, ohun kan ti a fẹran pupọ ti a si n ṣe itọju rẹ̀ daradara. Ero ti Ọlọrun rò si awọn Ọmọ Israẹli gan an ni yii. Oun ni Ẹlẹda aye ati ohun gbogbo ti o wà ninu rẹ̀, ati gbogbo eniyan; ṣugbọn Oun n fẹ fi oju rere pataki kan hàn fun awọn eniyan wọnyii ti Oun ti yàn lati maa pe orukọ Rẹ̀. O fẹ ki wọn jẹ́ orilẹ-ède mimọ́, ki gbogbo wọn si jẹ alufaa (Ẹksodu 19:6). A oo ri i pe wọn kuna patapata lati gbé igbesi-aye ti Oun n fẹ; ṣugbọn nipa Ẹjẹ Jesu a le mu ifẹ Ọlọrun ṣẹ ki a si jẹ olu alufaa fun Ọlọrun (1 Peteru 2:5).

## Ẹ̀jẹ́ Ainironu

Mose sọkalẹ lati ori oke o si sọ nnkan ti Ọlọrun sọ fun awọn eniyan naa. Awọn ileri ti Ọlọrun ti ṣe dara leti wọn; wọn si n fẹ gba ibukun ti Ọlọrun ti sọ nipa rẹ̀. Wọn yara jẹ́ ẹ̀jẹ́ lati ṣe ohun gbogbo ti Ọlọrun beere, ṣugbọn wọn ko duro lati ronu ohun ti o já si lati ṣe ifẹ Ọlọrun. Kò pẹ lẹyin ti Oun fi ogo Rẹ̀ hàn wọn, wọn gbagbe Oluwa patapata. Sọlomọni, ọlọgbọn julọ ni gbogbo aye wi pe, "O san ki iwọ ki o má jẹ ẹjẹ́, jù ki iwọ ki o jẹ ẹjẹ́, ki o má san a" (Oniwasu 5:5). Wọn ṣeleri lati ṣe ohun gbogbo ti Ọlọrun beere, ṣugbọn ko pẹ rara lẹyin naa, wọn ba majẹmu wọn jẹ́.

Ohun rere ti o pọ ju ti awọn Ọmọ Israẹli lọ paapaa ni Ọlọrun ṣeleri fun wa, Oun kò si beere nnkan pupọ lọwọ wa; ṣugbọn eniyan diẹ ni o n fẹ gbọran si Oluwa lẹnu lati ni awọn ibukun wọnyii!

Mose pada ni ọjọ keji sori oke, o si sọ fun Ọlọrun pe awọn Ọmọ Israẹli ti ṣeleri lati ṣe ohun gbogbo ti O wi.

## Ohùn Ọlọrun

Nisisiyii Ọlọrun sọ fun Mose nipa ohun ti o lẹru ti yoo ṣẹlẹ. Ni ọjọ mẹta si i Oun yoo ba Mose sọrọ lati inu awọsanma wá lọna ti gbogbo eniyan yoo fi gbọ́. Wọn ko ni le wi awawi mọ pe Ọlọrun kọ ni o rán Mose niṣẹ, ati pe ko mọ ju awọn naa lọ. Wọn o gbọ́ ohùn lati inu awọsanma, ṣugbọn wọn ki yoo ri ẹni kan.

Wo bi ayọ̀ awọn eniyan wọnyii yoo ti pọ to nigba ti wọn n lọ siwaju Oluwa! Mose kọ́ wọn lati wẹ ara wọn mọ́ tonitoni, ki wọn si fọ aṣọ wọn pẹlu. O yẹ ki wọn jẹ mimọ́ nigba ti wọn ba wa siwaju Ọlọrun gbogbo aye. Nigba ti ẹni kan ba wa siwaju Ọlọrun oun ko le fi ẹ̀ṣẹ rẹ pamọ rara, bi oun ba n fẹ esi adura rẹ, o ni lati kọkọ jẹwọ gbogbo ẹ̀ṣẹ rẹ na, ki a si dariji i, nigba naa ni oun to le beere nnkan ti o tobi lọwọ Ọlọrun. Aṣọ ti wọn n fọ̀ nihin jẹ apẹẹrẹ iwẹnumọ ti ọkàn wa nigba ti Ẹjẹ Jesu ba bo ẹ̀ṣẹ wa mọlẹ.

A fun awọn eniyan naa ni ọjọ mẹta lati mura silẹ; lẹyin naa ni wọn yoo pejọ si ẹsẹ̀ oke naa lati feti si ohùn Ọlọrun.

## Aadọta Ọjọ Lẹyin Ajọ Irekọja

O di oṣu kẹta nisisiyii ti awọn Ọmọ Israẹli ti fi Egipti silẹ. Awọn miiran gbagbọ́ pe nigba ti Iwe Mimọ́ sọ pe "li ọjọ kanna" o n tọka si ọjọ kin-in-ni oṣu. Bi eyi ba ri bẹẹ, ti Mose fi ọjọ kan lọ sori oke pada bọ̀, ti o si fi ọjọ kan mu esi awọn eniyan naa pada tọ Ọlọrun lọ, ọjọ mẹta ti o kù yoo jẹ ki o di aadọta ọjọ lẹyin Ajọ Irekọja.

Lẹyin ti a ti ṣeto igbesi-aye awọn Ọmọ Israẹli tán, wọn yoo maa ṣe akiyesi ase mẹta. Ajọ Irekọja ni ọjọ kẹrinla oṣu kin-in-ni; Ajọ Ọsẹ, eyi ti a n fi ọsẹ kan ṣe iranti ọsẹ pupọ (ọsẹ meje) lẹyin Ajọ Irekọja; ati Ajọ Agọ ti o bọ si ipari ọdun. Ajọ Ọsẹ (aadọta ọjọ lẹyin Ajọ Irekọja) ni a n pe ni Pẹntekọsti ninu Majẹmu Titun, oun si ni ọjọ ti Ẹmi Mimọ́ ba le ọgọfa eniyan ni yara oke, aadọta ọjọ lẹyin ti Jesu kú gẹgẹ bi Ọdọ-agutan Irekọja wa. Awọn eniyan gbagbọ pe a n ṣe Ajọ Ọsẹ yii ni iranti ọjọ ti a fi Ofin fun ni (Deuteronomi 16:9-12).

**Oke ti O N Jona**

Ọjọ nla naa de. Gbogbo eniyan pejọ si ẹsẹ̀ oke naa. Ọlọrun ti paṣẹ fun Mose lati pa aala kan sibẹ ki ẹnikẹni nipa ọfintoto tabi igboya ma ba sun mọ tosi ju bi o ti yẹ, nitori "Bi o tilẹ jẹ ẹranko li o farakan òke na, a o sọ ọ li okuta, tabi a o gún u li ọ̀kọ pa" (Heberu 12:20).

Ni owurọ ọjọ yii ariwo ta lori oke, eefin si n bì soke fiofio. Aara n sán, gbogbo oke naa si n mi titi bi isẹlẹ. Ohun gbogbo daamu to bẹẹ ti ẹru fi ba Mose paapaa. Nigba naa ni ipe dun kikankikan ti Ọlọrun tikara Rẹ̀ fun tabi awọn angẹli Rẹ̀ ti o tẹle E. Fere na tubọ n dun siwaju si i titi Mose fi ba Ọlọrun sọrọ. "Ohùn" kan fọ̀ si Mose lati ọdọ Oluwa wá o si paṣẹ fun un pe ki o goke wá. Ṣugbọn Ọlọrun ko i ti ṣetan lati fun ni Ofin. Oun mọ agidi ọkàn awọn Ọmọ Israẹli, O si ri i pe wọn ko ti mọ bi o ti lewu to lati sunmọ tosi oke naa ju bi o ṣe yẹ lọ. Nitori bẹẹ O rán Mose sọkalẹ lati kilọ fun awọn eniyan naa lẹẹkan si i, ki wọn tubọ rìn jinna si oke naa. Ati pe nigba ti o ba n lọ si oke pada, yoo mu Aaroni pẹlu rẹ lọ ki oun naa ba le gbọ́ nigba ti Ọlọrun ba fun un ni Ofin. A o fi Aarọni jẹ alufaa lai pẹ, o si yẹ ki o ni agbara Ọlọrun ki o ba le ni ọla niwaju awọn eniyan. Awọn eniyan naa bẹru aara ati manamana, ina ati eefin to bẹẹ ti wọn ko fi le sunmọ Ọlọrun. Wọn sọ fun Mose pe ki oun maa ba Ọlọrun sọrọ, ki o si wá sọ ofin Rẹ̀ fun wọn, "ṣugbọn máṣe jẹ ki Ọlọrun ki o bá wa sọ̀rọ, ki awa ki o má ba kú."

**Ifẹ Jesu**

Lonii ko yẹ ki ẹru ba wa nigba ti a ba tọ Jesu wá. Oun n nawọ ifẹ Rẹ̀ si wa; O kú lati dá ibinu Ọlọrun duro; O si ṣe ọna ti a le gba lọ si Ibi Mimọ́ julọ. Awa ti a ti fi Ẹjẹ Jesu wẹnu ni o ti sọ di ijọ akọbi ti a kọ orukọ rẹ̀ ni Ọrun (Heberu 12:18-24). Ṣugbọn niwọn bi Jesu ti fun ni ni ibukun ọrun ti o ṣe iyebiye bayii, a ni lati ṣọra ki a ba le gbe igbesi-aye wa lati wu U, ki a má ba jiya ti o pọ̀ ju ti awọn Ọmọ Israẹli, nigba ti wọn ṣe aigbọran si Ọlọrun.

**AWỌN IBEERE**

1. Nibo ni awọn Ọmọ Israẹli pagọ si lakoko yii?
2. Njẹ a ti gbọ́ nipa ibẹ rí?
3. Ki ni Ọlọrun sọ fun Mose pe yoo ṣẹlẹ lẹyin ti awọn Ọmọ Israẹli ba ti wẹ ara wọn mọ́ fun ọjọ mẹta?
4. Bawo ni Ọlọrun ṣe kede ifarahàn Rẹ̀? Ki ni ṣe ti awọn Ọmọ Israẹli fi bẹru?
5. Ki ni yoo ṣẹlẹ bi eniyan tabi ẹranko ba fọwọ kan oke naa?